The Chief Secretary to the Govert.


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. VI. No. 303 SATURDAY, DECEMBER 1, 1928 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



CHIEF SECRETARY'S OFFICE
5 DEC 1928
LAGOS

## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lowọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

N. *B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.


A. Lewis,

# To Stop Your Aches & Pains

*SIMPLY USE*




For more than 40 years Sloan's Liniment has been used throughout the World. It is kept ha dy in many thousands of homes to give quick, warming relief from the pains and aches of Rheumatism, Lumbago, Neuralgia, Sprains, Bruises and other severe pains. No need to rub Sloan's—it penetrates and kills the pain instantly.

*Sold by all Dealers.*

Wholesale:
FASSETT & JOHNSON, Ltd.
86, Clerkenwell Road,
London, England.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oșu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oșu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranșẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

EWO NI TI ILE WIWO ORU.

Irohin kan kan ni bi agbọsọ pe Ijọba npete ati ma jẹ ki awọn wolewole ma wo ile ni alẹ lati fi mọ bi awọn enia ti wa ninu ile kọkan si: a koi ti mọ bi otitọ ni agbọsọ yi tabi awọn aturọta bi elubọ ni nwọn nhọrọjọ bayi bi ologbo Idumọta.

ATATẸTẸ ȘIYAN KO DURO GB'ỌBẸ.

Erin ko pa ehin ni arọ *Monday* ọsẹ yi ni Odo Olusi nigbati onitẹtẹ kan jẹ ekeji; rẹ ni £2 4/- nigbati o ka'ra tan ẹniti a jẹ ni £2 4/- tun bọ coat rẹ silẹ pe on fi ta lọgan, ẹnikeji yi tun jẹ *coat* yi bakanna; nigbana ni ariwo ta, ti ẹsẹ nrọjo lara awọn mejeji: ki awọn ero igbonre ko wa ba wọn da si, ti ẹniti o jẹ £2 4/- si da £1 pada fun ẹniti o jẹ gbogbo owo na lọwọ rẹ.

## DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

ỌYẸ NDE "ALAGI-L'ỌPẸ."

Lati arin ọsẹ tokọja ni otutu oyẹ ti nfi ara ba enia diẹdiẹ eyi fihan wa wipe ki o to to bi ọjọ melo kan si, ọyẹ yio gadabu ni ilẹ yi. Ki Oluwa șe ni ti anfani fun awọn agbẹ loko.

ASUN-IGBADO TA, MẸLỌMẸLỌ O.

Awọn Aganyin ati ara Eko ti o nsun igbado tutu ta ti tun bẹrẹ gbe igba igbado sisun wọn, o yẹ ki a mọ gẹgẹbi a ti ngbọ wipe bi ajakalẹ arun ba nja lode bayi irufẹ igbado sisun bẹ ko yẹ larin ilu lati ma ta bikoșe eyi ti nwọn ba nse ta, nitoripe a gbọ wipe o jẹ ohun éwò fun ajakalẹ arun ,a si mọ wipe ko si ohun meji ti o njẹ aluba ni ede yoruba ju ilẹ-igbona lọ, nitorina iba dara ki olukuluku lọ wa ișẹ miran șe, ki igbado to de aiye nkan dandan ni adiẹ njẹ, a sọ eyi fun anfani ilu, ẹniti ko si gbọ ki si gbọ ki o fi șe ti ararẹ.

Ẹ KU ỌFỌ!

Gbukẹ ni a gbọ ti ọfọ ọmọbinrin Alhaji Sanni Giwa, ni ọjọ Jimọ ijesan,—a ki iya ọmọ ati Alhaji na, ki Ọlọrun fi idanwo na mọ bẹ, "Taohidi" gẹgẹ bi ede Imale, o dọwọ nyin o. Oluwa ki o si fori ji ọmọ na.

PẸKILAKOO.

Pẹkiriki li a șe alabapade awọn ilẹ gbogbo ti nwọn wo lulẹ ni Idumọta ni arin ọsẹ tokọja, eyiti a gbọ wipe awọn ilẹ-ile na gbogbo fi kuro lọwọ awọn oni-nkan.

ALIKALI KẸLẸKẸLẸ 'O.

Ni eyiti ọdun Keresimesi mbọ yi, a tanma wipe awọn Alikali ki yio șe jagidijagan wọn lọtẹ yi, bi nwọn ba si șe ẹwẹ bi nwọn ba kan idin ninu iyọ, a jẹ wipe nwọn a fi șe ti arawọn, awa șe ti wa na.

IGBIMỌ AȘOFIN.

Ipade Igbimọ Așofin bẹrẹ ni ọjọ Satide to kọja ni abẹ Alagba Ọlọla F. M. Baddeley KT; C.M.G. A si tanma wipe awọn Așoju-ilu wa meji Ọlọla Lọya Moore ati Ọlọla Lọya Doherty ki yio șai lọ. Anu șe wa wipe Ọlọla Dokita Jones kole lọ lọtẹ yi gẹgẹbi a ti ngbọ wipe o mbẹ ni ilu Saro lọwọlọwọ yi.

COR—AURS—KASSOX ATI AYA ONI JẸ NI KI (O'LONJẸ NI A KI).

Ere pataki kan nwọn o șe ni ile-ẹgbẹ (Glover Memorial Hall) ni ọjọ Alaruba ọjọ karun oșu yi ni abẹ Alaga Dokita Samuel T. Wills M.D; L.R. C.P.E., ati awọn sanmari gbogbo.

AREDE TO NI ARIN-RIN!

Ni ọjọ Tuesday ijọ kẹtadilogbon oșu November 1928, ni Ọgbẹni Albert Edward Oludọlapọ Bright gbe omidan Adel Ọlatẹju Ẹtti ni iyawo ni Ṣọși Bethel ni agogo meji ọsan ninu awọn ẹniti o wa nibi igbeyawo ni L. Ayodele Bada, Mr. and Mrs. John Adolphus Bright, Joseph Olugboyega Bright,

Frank Montagu Macauley, Alaba Thompson ati awọn Jakanjakan miran. Adura wa nipe ki Ọlọrun ko ṣe wọn ni ọrẹ ara wọn.

Ni ọjọ Wednesday ijọ kejidinlọgbọn oṣu November ni awọn ẹni wọn yi Mr. and Mrs. A. E. Oludọlapọ Bright, Mrs. Frances Bright ati Miss Felicia Frances Ashabi Bright wọn wọ ọkọ Reluwe lọ si Bukuru Oluwa ko ṣọ wọn ni ọhun, ko si mu ẹniti o sin wọn lọ bọ ni alafia.

Inu wa dun pupọ lati jihin fun yin wipe Ọgbẹni wa Daniel Ayọdele Oluṣakin Bright nri alafia nipa ewu to wu to si ti wa nile ni ọjọ diẹ sẹhin. Ọlọrun ko ṣe iwosan ko si fun ni alafia ati ẹmi gigun, ko si pada si ẹnu iṣẹ rẹ pẹlu ara lile.

Ni ọsẹ to nbọ ni agbara Baba ao tẹ idajọ ẹjọ Akarigbo ati Jimbo Apena ni Ede yoruba ati irohin Igbimọ Aṣofin nla ohun ti awọn ẹni wa bere ni ọhun ati esi ti wọn fun wọn ni ede yoruba. Ni ọsẹ yi a ko le jihin gbogbo rẹ.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ENIA KO DA BI ALLAH.

---

## ORI ADẸTU NPE ARAN, ORI ADE ARAN NPETE ATI JẸ ỌBA.

Inu wa dun pupọ nigbati agbọ wipe gbogbo Jamat to wa ni Mọshalaşi Itafaji (Faji Mosque) patu pọ, lati yan Ọgbẹni Mohammodu Lawain Adeniji si Imam ti yo ma kirun fun won, lẹhin igba ti Lemamu wọn Ologbe Bakare Ikandu yi eyi yi ni pe on ni awọn yio we Lawani Imam ti Moshalaşi yi fun, gẹgẹ bi ifi ohun ṣe ọkan wọn ni inu ipade ti wọn ṣe kẹhin ni ọsẹ to koja ni ọjọ kẹdogbọn oṣu November ti ọdun yi 1928. A gbọ wipe Imam Jinadu Mati ti Mọshalaşi Isalẹ-angun jẹ okan ninu awọn to ṣe ipade na. Asi ki Imam Mati gidigidi oku işẹ adinni. A si tun ki Yesufu Igiola olori awọn Ansarudeen to wa ni Moshalaşi Ita Faji na pẹlu awọn ijọ rẹ. Ati awọn Baba wọn bi awọn ọgbẹni Asani Afoke pẹlu awọn ẹgbẹ rẹ, ati awọn Jamat to wa ni Mọshalaşl na wọn tẹle, gẹgẹ bi owe awọn Baba wa pe omi ki ni oju ipọn ka ti ẹhin pọn, wọn ku atogun.

---

## OHUN TI ỌWỌ ẸNI KO BA TO, A KI FI ARUGỌGỌ FA.

Anu ṣe ni fun ọgbẹni ara gbo kan eyi ti o wa ṣe Igbeyawo ninu ọsẹ yi ni Church Iroloya pe ko tilẹ mọ ohun pataki ti o wa ninu Igbeyawo, ẹniti o ma gbeyawo ti ko yan God Father God Mother and Best man, iyoku iregbe ninu Church ni ọgbẹni yi ti nigbẹ fun awọn nkan wọnyi, iba dara pupọ bi o jẹ pe ogbẹni yi bere lọwọ awọn agbalagba ki o to dawọ le e boya wọn ba la gbogbo rẹ ye daradara. A gbo pe nşe ni ọgbẹni yi la da ọka lode fun Iyawo lati ba jẹ sun lalẹ.


# KERE O!

OYINBO KESSLER GBE TANA DANU, O GBE ...I DE.

Irin-işẹ Gbẹna-gbẹna to dara ju ti nwọn ti nlo fun iwọn adọta ọdun sẹhin wa fun tita ni Şọbu **Kessler.**







Ẹ ba mi lọ si Şabu na, ẹ o ri ti nyin yan nibẹ, ọpọku oyọku ni owo rẹ, iba diẹ ni o wa. Aworan Irin-işẹ wọnyi ni a ya sinu iwe yi fun nyin yi. Lọgan lẹ o ri ra.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Şabu Oyinb'o KESSLER ni No. 7, Labinjo Lane, ni Eko.







Ẹnyin ara Eko, ara Oke ati ilu miran, gbangba dẹkun, kedere bẹwo, Şabu Kessler ti kuro ni mọri nkan firi irohin ko to afojuba. Ẹ ma şe gbẹhin ki ẹ to ra ti nyin, ki ẹ ma ba joku Ologbo.

## SHORT STUDIES ON YORUBA WARRIORS.

By Agbaje.

[*Copyright*]

## BALOGUN IBIKUNLE.

### His Early Days.

Ibikunle, whose name in after years played so great a part in the making of Ibadan country in Yorubaland, was born at Ogbomọṣọ: his mother was of Ẹgbado tribe. There can be little doubt that when he attained his majority he came over to Ibadan in search of adventure: this was not uncommon in those days of internecine wars in

### His Time of Trial

He was not exempt from the usually known fate which generally befall: one at the outset who is marked for possition of worth in after life: for we find him shabily treated by his first wife, when on an occasion, he returned home from an expendition overcome with fatigue, and hungered: he bought some agidi balls and took some soup prepared by the wife specially for herself—mark the selfishness! and invited his son Babayẹmi born to him by this selfsame woman to partake of the meal: imagine, if you please, the temper of the wife on her return home only to learn that her hunsband has been helping himself to her soup-pot without her autharity or sanction—a think inconceivable !!! she called her husband names and emptied the remaining soup on his head: Ibikunle, be it remembered, did not meet force with force *then*, but simply asked his son to leave the soup severely alone: the son, in obedience to his father, drank with him the liquid-form to which the remaining agidi balls were reduced: the future general did not forget this incident.

Eventually our hero was ascending the success ladder gradually; he was made the General of the Ibadan forces in succesion to Ọdẹrinlọ, on or about 1841, as time wore, on the thought of revenging himself on his once heartless wife prevailed with him. One day he asked all his wives, 70 in number; to cook him specially grepared *Ilasa* soup in honour of a day for the propitiation of his Guardian-spirits: each wife tried to vie with one another for the best result: in the twinkling of an eye, 70 soup-ports were in readness: the old wife taking particular care in cooking her own with dried bush-hog for culinary effect: all the pots were placed in a paticular spot at Ibikunle's command: after this he ordered every one before him to make room as he desired to be left alone for sometime: on the spot being clear, he called Babayẹmi's mother and asked her whether she remembered her past treatment to him: the former r e p l i e d in the affirmative: Ibikunle then began to empty the boiling soup on her bare head, and when the pain became excruciating, Babayẹmi involuntarily prostrated before his father and interceded for his mother, and immediately, Ibikunle desisted, saying his son's obedience to him that day has saved the mother from being scorched to death: but one thing is significant in this nnhappy episode and that is, since his wife's illtreatment as stated, Ibikunle ceased all connextion with her as heretofore, though she was allowed to remain in the house until her death

### Gospel Mission to Ibadan.

During the time Ibikunle was the Commander-in-Chief at Ibadan his country of adoption, Oyeṣilẹ was the Balẹ who was generally known in history as Balẹ Olugbode: in whose time Christianity was introduced to this country by the C.M.S. through that great and good man, the Rev. David Hinderer: the warm welcome accorded the German pioneer Missionary speaks volumes for the measure of prosperity which was noticeable, and enjoyed by the Ibadans at the time.

### Wars.

The principal wars in which Ibikunle took part in his time and which were won are as follows:—

The Battle of Ara
,, ,, ,, Ẹfọn,
,, ,, ,, Ijaiye, (1859–1862.)
,, ,, ,, Kutujẹ, (1862–1864.)

Ibikunle's exploits were varied and numerous: he defended Ibadan against all external incursions, ably assisted by his lieutenant Ogunmọla: in his time, many territorial possessions were added to Ibadan.

### His Death.

On the eve of the battle of Kutujẹ, (1862) he was accidentally wounded by a youngman whom he ordered to cut a dog into two *at a single stroke* for a sacrifice to the god Ogun: the cutlass escaped from him at a wave of the hand, and made a deep gash in one of his thighs: the wound proved fatal and the victim was buried with military honours at Ibadan.

Thus passed away in 1864, Ibikunle, one of the greatest generals the Yoruba race has produced.

### His Congnomens (*Oriki.*)

Ibikunle Oloke,
Agbangba Asẹ,
Balogun Atẹni bi aje,
Iagun a to bi aila,
Alagbala jaiya-jaiya baba Kuẹjọ,

Alagba 'Bikule j'oko ęlomiran lọ,
Bi yio ba wọn ja toju-timu ni fi pọn ṣęṣẹ,
Apọnloju 'ja ṣęrişęri,
Ọkunrin kiribitipi,
O ki lọwọ ki lẹsẹ bi ogidan,
Ẹni duro de erin, o duro de 'ku,
Ẹni duro d' ẹfọn duro de 'ja,
Ẹni duro de egun alagangan,
Ọrun ni nfẹ lọ.

---

ORI V.

## IGBOIYA.

*( Translated from "Character by Dr. Smiles" ).*

APA KINI.

---

Ire ti awọn ọkunrin ati awọn obirin ti o ni igboiya ṣe fun aiye ko kere. Aiya nini lasan bi ti aja-ọdẹ ko ni a nwi; bẹni ki isi ṣe pe aja-ọdẹ nikan lo gbọn ju gbogbo aja lọ.

Igboiya ti a nri ninu iṣẹ ti ki iṣe ti aṣehan—eyiti ima farada ti ki isi kọ iya-kiya nitori otitọ ati ẹtọ—eyi ni iṣe ojulowo igboiya ju ti ajagun gboye lọ.

Igboiya ninu iwa rere ni a fi imọ ọmọluwabi lọkunrin, lobirin,—igboiya lati wadi ati lati sọ otitọ; igboiya lati ṣe etọ: igboiya lati ma ṣe eru; igboiya lati ma fi ara silẹ fun idẹwo; igboiya lati ṣe iṣẹ eni. Bi enia, iṣe-ọkunrin iṣe obirin ni, ko ba ni iwa rere yi, ko si ọgbọn rẹ ti iwa rere miran ti o le ni ko ni fi bajẹ.

Ninu ijakadi ati iṣoro ni ẹda fi nlọ siwaju ati siwaju, awọn akọni enia ni o si ṣe eyi—awọn aṣiwaju ninu ogbọn—awọn Ọga ninu iṣẹ a nwa ọgbọn kan tabi niti a nwa ilu titun kan, awọn ti o ni ifẹ ilu san, ati awọn onişẹ san lọna iṣẹ-kişẹ. Ko si otitọ nla kan, tabi ọna ẹkọ pataki kan, ti ko jẹ pe ki awọn enia to gba a, ebu, ọrọ aidara ati inunibini a ti pọ. Heine ni "Nibikibi ti o ba ri olotọ enia ti o nsọ tinu rẹ jade, ni Golgotha nbẹ."

"Ọpọ ni ifẹ Otitọ, nwọn si fi gbogbo ọjọ aiye wọn
Wa a kiri ninu iwe,
Nikẹhin nwọn ri itẹlọrun ere lala wọn
Nigbati o bọ agbada rẹ silẹ fun wọn,
Ọpọ wa a ninu igbagbọ ti ko ni ayọ,
Ọpọ gbe ọwọ lọwọ ṣọkun wa,
Ṣugbọn awọn ara wa wọnyi, ja fun
Nwọn gbe iku ta ṣişẹ fun,
Nwọn ni ifẹ rẹ tobẹ ti nwọn ku nitori rẹ,
Nwọn si tọ adun aṣepe rẹ wo."

A da Socrates lẹbi iku, a si fun ni iwọ mu ni *Athens*, nigbati o di ẹni ọdun mejile-ladọrin, nitorina ẹkọ rere ti o nkọ ni lodi si ti aiye igba na. Awọn olufisun rẹ ni, o nba awọn odọmọkunrin Athens jẹ, o nkọ wọn ki nwọn ma nani awọn orişa ilu. Ko bikita fun iwa aninilara awọn adajọ ti o dajọ fun, ati fun oju dudu awọn ara ilu ti ede rẹ ko ye. Titi o fi ku ni o nkọni ni ẹkọ pe ẹmi enia ki iku; awọn ọrọ ikẹhin ti o si sọ fun awọn Adajọ ti o dajọ fun ni. "Akoko to ti a o tuka—"Emi yio ku, eyin yio wa laye; şugbọn ko si ẹniti o mọ ewo ninu mejeji ni o dara ju afi Ọlọrun."

Melomelo ni awọn ẹni nla ati awọn ọlọgbọn ti a ti ṣe inunibini si nitori ẹsin! Nwọn dana sun Bruno laye ni Rome, nitori o sọ pe ẹkọ ti o gbilẹ nigbana ki işe ọna. Nigbati awọn Adajọ ti o wadi ọran rẹ da a lẹbi iku, Bruno wo won bintin, o ni, "aya nfo eyin ti ẹ ndajọ ju emi ti ẹ ndajọ fun lọ."

Lẹhin tirẹ ni Galileo ẹniti ẹkọ ọgbọn rẹ fẹrẹ ma to ti ajẹriku ti a sọ ọrọ rẹ. Awọn Alufa fi wasu, nwọn ni o nkọ awọn enia pe aiye nyi, ko duro lojukan; nwọn pe e lọ si Rome ki o wa sọ ti ẹnu rẹ nipa ti ẹkọ ti o lodi ti o nkọni; ẹni adọrin ọdun ni nigbana Nwọn si sọ ọ sinu tubu; a tilẹ ro pe nwọn jẹ ẹ niya oro nibẹ pẹlu. Nwọn ṣe inunibini si i debi pe nwọn mu oku rẹ lọta pẹlu, Pope kọ ko jẹ ki o ni orori.

Nwọn ṣe inunibini si Roger Bacon (Franciscan Monk) nitori o nkọ ẹkọ ọgbọn ijinlẹ; nitoriti o nkọ Chemistry nwọn sun ni ẹsun pe alalupayida ni işe. Nwọn tẹ awọn iwe ti o ṣe ri, nwọn si sọ ọ sinu tubu, o ṣe ọdun mẹwa nibẹ; Pope mẹrin ni o si jẹ ni şisẹ-ntẹle ninu ọdun mẹwa na. A tilẹ gbọ pe inu ẹwọn ni o ku si.

Pope yọ Ockham, ẹniti o kọkọ şişẹ a nwadi ọna ẹkọ ọgbọn ni England, ni ijọ; nwọn wa a kuro ni

ilu lọ si Munich nibiti o gbe ku si. Ọpẹlọpẹ Ọba Germany lara rẹ nigbati o wa ni Munich.

Awọn adajọ ti o wadi ọran Vesalins ni aladamọ ni iṣe, nitoriti o nkọni ni ẹkọ bi ẹda enia ti ri, bakanna bi nwọn ti sọ niti Bruno ati Galileo nitori nwọn nkọni nwọn nfi oye awọn ohun ti o wa loke Sama,—Orun, Oṣupa ati awọn irawọ, ye ni. Vesalins tilẹ gboju gbaya la oku enia lati le kọ ọgbọn bi ẹda enia ti ri, aṣa ti a fẹrẹ le sọ pe a ko ri ri nigbani. O fi ipalẹ ọna ọgbọn kan lelẹ, ṣugbọn ẹmi rẹ lọ si. Nwọn da a lẹbi iku, ṣugbẹn Ọba Spain bẹbẹ fun ko jẹ ki nwọn pa a; Nwọn ni ki o rin irin ajo lọ si Ilu Mimọ; lọna nigbati o ndari bọ, o ṣi wa ni ọmọde-mẹsọ, arun iba ati ebi inu pa a, o ku yẹpẹrẹ ni Zante—o ku nitori ifẹ ti o ni fun ẹkọ ọgbọn.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

## ANABI NI Ẹ MUWA.

Ọgbẹni Ganbari Onibara kan wa ni Opopo Ọnala ati Oko Awo nigbakugba ti a ba nkọja ni a ma nri Ọgbẹni Onibara na nibẹ ṣugbọn a ko ṣe akiyesi ohun ti o ma nwi nigbati o ba nṣagbe, pe Anabi ni ẹ muwa lo ma nke, o wa yani lẹnu pe ki tilẹ wi nkan miran ju Anabi ni ẹ mu wa lọ, Onibara ni, tabi o npaṣẹ?

## ALỌ.

## IDARAYA AWỌN ỌMỌDE.

Alọ o.

1. Ngmm.

2. O nlọ si Ọyọ, o kọju si Ọyọ, o mbọ Ọyọ, o kọju si Ọyọ.

3. Ojo pa Lukọtun, ko pa Jaguna.

4. Aja mi ṣẹkẹrẹ-ṣẹkẹrẹ ṣẹ, aja mi ṣẹkẹrẹ-ṣẹkẹrẹ ṣẹ, ojumọ ki imọ, ki o ma jẹ adiẹ funfun.

5. Ka mu ragba-ta-ragba, ka mu ragba-ta-ragba ka mu ragba ka fi takuta gba.

6. Agba meji duro li etido a ko mọ ẹgbọn a ko mọ aburo.

7. O ku atọdunmọdun, o ku atọdunmọdun a ba li oke odo o nfẹyin kẹ ẹ.

8. Iyawo rọgbọdọ a ṣowo ma wọ ile.

9. A bẹ lori, a bẹ lọrun, o ni on ka ṣai jẹ oye baba on.

10. Obinrin rọgbọdọ larin ẹgun.

11. Oruku tindi-tindi oruku tindi-tindi oruku bi igba ọmọ gbogbo nwọn jẹ atiro.

12. Ṣẹṣẹ ni igbọ, wọwọ ni ọdan, gere li apata, Ọpọnti ko ni oru, Ajagun ko ni apata, Oṣepo ko ni ata, Ọranwu ko li kẹkẹ: meje la pa a meje la ja a.

ALADE.

## ITAN ALADE ỌBA IPẸRU NI IJẸBU RẸMỌ.

Mo juba o Ẹnyin Alagba,

Mo fẹ sọ itan ara Ipẹru diẹ si eti igbọ awọn ti o nko irira ara Ipẹru si eti awọn Ijọba Igesi awọn olotọ ati awọn olododo. Ade ti Ọba Alapẹru gba kin ṣe Ade eru rara o, Oyinbo mọkanla li o wa nibiti Ọba Alapẹru gbe de Ade tobinrin ti ọkunrin awọn ọlọla oyinbo. Mo ro pe wọn wa ninu aṣẹ ati ninu ọla Gomina ni. Awọn ara Ijalu gba Ipẹru Ile Ifẹ ni wọn ti wa. Awọn ara Ile Lisa ti Ipẹru Itu Imọsan Ijẹbu Ode ni wọn ti wa. Awọn ti o njẹ Ọba Ipẹru titi di oni. Ijẹbu Ode ni wọn ti wa. Ọmọ Ẹkẹta Olu ni ara Alapẹru ni Ijẹbu Ode ni lailai ri. Ipẹru ko nmu ẹsin ọdun lọ si ibomiran, Ijẹbu Ode ni ara Ipẹru nmu ẹsin ọdun lọ daradara gẹgẹ bi itan ti mo gbọ ni ẹnu awọn baba nla wa. Emi J. A. O. Shomade ọmọ Ọba ọlọla Alapẹru mo ro pe emi ju ọmọ ọdun marunlelogoji 45 years lo nisisiyi o. Ọmọ Ọba wa agba ọlọla julọ Awujalẹ, obinrin ni o mu Ade wa si ilu Ode ni ilẹ Rẹmọ ni Ode. Ode peju ni ki awọn oyinbo to ro Agba si Ijẹbu Ode ni 36 years ago awọn kan ba awọn ara Ode ṣe ọtẹ titi wipe awọn fẹ gba Ade na kuro ni ọwọ awọn ara Ode. Ọba Ode ti o wa ni ori oye nigbana, Ọba pataki ni ki ṣe Ọba yẹyẹ rara. Nitori wọn mura ogun jija lati fi gba Ade na pada ni ọwọ Ọba Alaye Ode ko ṣe ṣe rara ni igbana ni wọn sọ wipe ki awọn ara Ode gbe Ade na si arin meji Ipẹru ati Ode wipe ki awọn ma yinbọn si ara awọn; ti wọn sọ pe ẹnikẹni ti ọwọ rẹ ba to Ade nigbati awọn ba nyinbọn si ara awọn wọn ni on ni ko gbe Ade na lọ si ilu tirẹ awọn ara Ipẹru gba fun wọn bẹ nigbati ara Ilu ma jẹki oniwun ṣe tabi ara awọn ako tirẹ ba tẹni si dahun wipe ilu Ipẹru ni awọn ma gbe ogun ti awọn gba bi awọn ba nbọ awọn ara Ipẹru sọ fun wọn wipe ki wọn tẹ ọkọ lọ jagun na wọn kọ wọn ni Ipẹru ni awọn ma gba lọ.

(*Koi pari*).

Emi ni tiyin nitotọ,

J. A. O. SHOMADE.

***EKO AKETE***

EKO, SATURDAY, DECEMBER 1, 1928.

## KOTU ENIA DUDU L' EKO?

### KAMARI ! KAMARI ! !

Orişirişi işẹ ni awọn Igbimọ Aṣofin Ọba ti nşe lati Satide to kọja wa titi di ọsẹ yi ọkan ti o si jẹ pataki ninu awọn işẹ yi ni akatakiti ti Ijọba nşe ninu Ajọ Igbimọ na lati sofin d i d a Kotu Enia Dudu *( Native Court )* silẹ l' Eko :

Kini pataki ohun ti o fi ero aitọ yi si ọkan Ijọba lati tubọ fọ gbogbo nkan loju ni ilẹ yi nipa irufẹ ofin bayi ? Lẹhin igbati Kotu awọn Ọlọpa mbẹ ti Kotu Ganran si mbẹ pẹlu kilo mu sababi titun fẹ da Kotu Enia Dudu silẹ bayi, ko si ibikibi ti Ijọba ti da Kotu Enia Dudu silẹ ni ilu Oke ti ko ıni awọn enia ara ilu ibẹ lara, şe ni koipẹ yi ni a ri ka ninu iwe "*Daily News*" pe bikoşe ọpẹlọpẹ didasi ti ọkan ninu awọn Oyinbo Adajọ Ijẹbu-Ode da si ẹjọ ọkunrin kan ti o jẹ ara Ijẹbu-Ode, pe ọkọnrin na ko jẹbi ẹsun ti a sọpe awọn kan fi şun ni Kotu tabi Igbimọ Enia Dudu n i Ijẹbu-Ode pe oluwarẹ nşe owo şile, ẹwọn ọdun gbọrọ ni a sọpe awọn Kotu Enia Dudu ilu na iba gbesi.

Kotu kan ti o jẹ pe irira tabi ọmọ ta nun ? Ni o fẹrẹ wọpọ ninu işesi wọn gẹgẹbi a ti nri iro Kotu miran fi o jẹ ti Enia Dudu ti ilu Okere gbọ. kọ lo wa yẹ ni iwoyi lati da si Eko : ọran ha ti to eyi ki awọn kan ni ọdun diẹ sẹhin bẹrẹsi yajule ma tọka fun awọn Ọlọpa pe Lagbaja Tamadu, Lakaşegbe pẹlu awọn ti nwọn sọko si ile wọn nitorina ki awọn onişẹ-Ọba wọnyi mu wọn ? Ani şe ọran ha ti to eyi ki o jẹ pe o jẹ aşa awọn kan lati ma lo para ọdọ awọn Onilu pe nşe ni la'mọrin bẹrẹ si wo wọn loju kọkọrọ. Ijọba mọ pe ọtẹ, aifẹni, ati idaru dapọ mbẹ larin ara Eko tobẹ ti ko fi le jẹ ki ẹnu ọpọ enia papọ lati şipẹ fun Ijọba fun ifẹ inu wọn lati sofin ti awa ara ilu le ka si ofin kofin gẹgẹbi ofin dida Kotu Enia Dudu silẹ ni Eko.

O wa daju gbangba pe awọn igi oro ti Gomina Lugard ti tẹ si *Nigeria* ni akoko igbati o şe Gomina ibi na ni Ijọba Eko ode oni nlo lati tubọ da gbogbo nkan ru, lati tubọ mu inira ba Eko, ani lati tubọ sọ Eko di Ọrun Apadi fun ara ilu.

Ẹ jẹ ki a ya bara lati fi eyi ye nyin: ni akoko Gomina Lugard ni o daba lati gba gbogbo Şukuru sabẹ Ọba awọn Ọga Ile'iwe ti kosi labẹ Ọba ta ko nigbana: o si jọgọnu : şugbọn loni nkọ gbogbo Şukuru ko ti di ti abẹ Oba bi, ofin eyiti Ijọba sọ ni akoko Gomina Thomson yi, ti o si mu ọgọrọ awọn ọmọ'lewe di alarin kiri nitori lilo ti awọn Ijọba nlo ofin yi. A Igẹsi ọwọ ti ẹ ngbe fi jọba lori *Nigeria* lo mu wa şẹ nga ọ

Ninu ofi ọ la yi kọ ni Ijọba tun nlẹ sofin dida Kotu Enia Dudu silẹ l' Eko. Tani ninu ẹgbẹ amoye to mbẹ ni ilẹ yi ti o ni pe awọn Kotu ti o ti wa ninu eyiti nwọn nrojo o n i r u r u nibẹ ko tẹ on lorun. Ni koipẹ yi kọ ni Ọgbẹni Olukoya Ọnabayọ kọwe kan şinu "*Daily News*" ti *Wednesday* ọsẹ yi si idahun si ẹnikan ti o kọwe gbun, a şebi Ọgbẹni Olukoya Ọnabanjọ pe Kotu Enia Dudu Ijẹbu-Ode ni Kotu Bitibiti, ti ko ba ni idi a ko rope Ọgbẹni Ọnabanjọ na le gboju gbaiya pe irufẹ ede bẹ ki o si fọwọ si iwe na ni isalẹ rẹ pe on lo kọ.

Ara Eko ti Ijọba ba lọ sofin dida Kotu Enia dudu silẹ ni ilẹ yi a ko mọ le mọ ọmọ ti o le bi lẹhin ọla : ẹlomiran le ma sọpe Eko ntẹ atẹsiwaju ati pe gbogbo nkan lo nlọ dede . Şugbọn ọpọ enia to mọ pe Eko oni ki şe Eko kan ti o ni ayọle mọ nitori inira nla ti o wa ti ibanujẹ fẹrẹ le ına kọlu ara wọn, lori aisi işẹ, aisowo aibalẹ ọkan.

Kotu enia dudu l 'Eko ?

**Kamari ! Kamari ! !**

## ẸNITI O KUN'LẸ TO GBIN IKA ORI ONI'KA NI IKA IHU LE.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*.

Mo bẹrẹ f'oji,

Ohun ti o gbilẹ lọkan ọpọlọpọ awọn ọmọ Anabi Adamọ ni samani ti a wa yi ni iwa ika, iwa bi o ba ki o mu, bi o ko ba ki o bu lẹsẹ, ṣugbọn awọn irufẹ ẹni bẹ gbagbe wipe ọjọ kan mbọ ti ilẹ yio mọ lẹhin oluwarẹ tabi ilẹ yio ṣu lẹhin oluwarẹ ti nwọn o si tun ma ṣe aiye lọ bakanna lẹhin oluwarẹ.

Ọpọlọpọ awọn aliamọkan omiran yio sọ wipe aiye bajẹ, a fẹ lati sọ fun iru awọn ẹni baun pe aiye ko fi igba kan bajẹ arara, lati ọjọ ti Olodumare ti ṣe ẹda rẹ, awọn ẹda inu rẹ lo bajẹ, ni o si balumọ pelu, ni nwọn ghagbe wipe awọn fun arawa kọ li a da ara wa, nipa iwa buruku gbogbo ti ẹlomiran fi nṣe ayọ ti o si nhuwa bi "tanimamuni" ni ọkan rẹ.

Awọn iwa buburu gbogbo ti awa Ọmọ Anabi Adamọ nhu si ara wọn, li o nmu nwọn ri onuiru nkan ki nkan ti ko yẹ fun wa gẹgẹbi aguntan Oluwa.

Awa ni igbagbọ wipe kosi ohun ti o le da ṣe lẹhin Sati, ni iwọn igba ti a ba mbẹ ninu adanwo ti ko ba ni lara mu dajudajn ko sẹhin Ọlọrun, ṣugbọn lode ti oni, aiọwọfa ọmọ Anabi Adamọ lo ṣe okunfa ọpọlọpọ ohun musiba ti ẹlomiran le ma ri.

Nigbati a ni Ọlọrun so Oñu, ti o si ni lã awọn Ojiṣẹ Rẹ fi jiṣẹ fun wa ti awọn Ojiṣẹ Ọlọrun si dide pẹlu ibẹru Ọlọrun gẹgẹbi awon papa ti jẹ ẹda enia bi awa na, ti nwọn si fi nkọ wa wipe nkan bayi ni Ọlọrun fẹ nkan bayi ni Ọlọrun ko fẹ, anfani awa ara wa ni, eyi fihan wa wipe Ọlọrun nfẹ wa gẹgẹbi a ti jẹ aguntan Rẹ.

Nko la idi ohun ti mo fi sọ fun nyin nisisiyi pe fun anfani awa ara wa ni lati ọjọ gbọrọ ni a ti ni igbagbọ pe, ti a ba tẹ Ofin Ọlọrun leti ara wa ni a nṣe kosi eyiti o kan ti Ọlọrun nibẹ.

Ọlọrun ni iwọ ko gbọdọ ya erekere kan fun ara rẹ itumọ rẹ ni wipe iwọ ko gbọdọ ṣe iru ẹda ti On ṣe, ki irufẹ awọn ẹni bi awọn ti nwọn ngbe Oriṣa bi ere kan kalẹ ti nwọn pe ni Ọlọrun, ni iwọn igba ti o ba ti jẹ wipe awa fun ara wa ni a fi ọwọ ara wa ṣe e, eyi fihan wipe ohun asan ni, gẹgẹbi ọrọ Oniwa pataki kan ati pẹlu ara wa ni a nṣe.

Lẹhinna Ọlọrun ni ki a maṣe ṣe afojudi si baba tabi iya wa, ki ọjọ aiye wa le pẹ, iyẹn ni wipe ki ẹni wa le gun, ṣugbon ode ti a wa nisisiyi yatọ pupọ ode jamba ati ode ika.

Ọlọrun ni a ko gbọdọ pania, a ko gbọdọ ṣe panṣaga, a ko gbọdọ jẹri eke si ọmẹ ẹnikeji wa, ati bi iru ohun ti ko dara bi ki a ma purọ ma ara wa, ki a ma lọ nkan buruku mọ ara wa lọrun, ki a ma le bo ara wa ni aṣiri owo lasan nitori Ọlọrun, ki olowo ma le ṣanu talika ati awọn iru iwa gbogbo ba wọnni.

Gbogbo awọn ohun ti a ka wọnyi, mo fẹ ki ẹ da mi lohun, fun anfani ara wa ni tabi fun anfani ara wa kọ? Bi a ba le ri ẹni da wa lohun pe fun anfani ara wa kọ ki o si fi iwe Ọlọrun kan bi Bibeli tabi Alkurani kun idahun rẹ lẹhin, inu wa yio dun pupọ a jẹ wipe fage ọrọ li a nsọ.

Ohun pataki ti a nsọrọ le lori loni gan ni iwa ika iwa jamba ti ko jẹ ohun pataki ni ọkan ẹlomiran lati ma hu, ni igbagbọ pe ti awọn ba de ọrun awọn yio jumọ ma lọ ro o, iyẹn ti o ba jẹ wipe awọn ẹni bẹ ni igbagbọ otitọ pe a o bo wa mọlẹ, a o ji wa dide a o si jihin gbogbo iṣẹ ti a ba ṣe ni igbesi aiye wa.

Ṣugbọn awa ni igbagbọ si ọrin waka ti awọn Imale ma nsaba nko ti nwọn ba nṣe iwasu wọn pe—"A ki igbin alubọsa ko hu ẹfọ, ohun a ba gbin ni yio hu ara aiye." Dajudaju ohun ti a ba gbin ni yio hun lẹhin ọla.

Ṣugbọn awa nsọ loni pe "Ẹniti o kunlẹ to gbin ika ori onika ni ika ihu le."

Ẹ gbọ bi itan kekere yi ti wi, nitori bi a ba ni ki a ma fa ọrọ Oluwa yọ gẹgẹbi ko ti dara lati ma hu iwa ika fun ara wa, ilẹ yio kun.

"Ni ọjọ kan Ogun lọ tẹ, ifa lọdọ Ọrunmila, eyiti awọn ọbọ lagido omiran sọ di (Ọrun lo mọ ẹniti yio lá), ida kan ṣoṣo lo si mbẹ lọwọ Ogún ti o fi nṣe ọkunrin."

Ọrunmila ni o dara, ki o mu ida kan ṣoṣo na wa, ti o fi mbọ fun un, Ọrunmila si fiida na ti si kọrọ yara ile rẹ.

Nigbati Ogun ko ni ida mọ, o wa nṣe jẹjẹ kiri, o si bẹrẹ si ṣere bi were-wrere kakiri ode awọn ọmọ wẹrẹ ati agbalagba si nwọ tọ o lẹhin: nwọn ko tun sa fun un mọ, nitori ida ti ko ni mọ.

Ni ọjọ ti Ogun ṣere bayi de ọdọ Oriṣa, ti on ti ọwọ enia lẹhin rẹ, ni Oriṣa bi i lere pe kini ṣe ọ ti o fi nṣe bayi? Ogun dahun pe airikanṣekan li o ba eyi ba on, nigbati Ọrunmila ti yan ida ọwọ on fi rubọ ti on si ti fi fun un, kosi ipa kan ti on tun le ṣe mọ, Oriṣa ti o ti ni Ọrunmila sinu tẹlẹtẹlẹ kọ Ogun pe ki o yara lọ gba ida rẹ lọwọ rẹ tabi ko mọ wipe ida ni o fi nṣe ọkunrin dan?

Bi Ogun ti lọ tan bẹni Ọrunmila yara gbe Ifa silẹ, lati wadi ohun ti o fa sababi ti Ogun tun fi wa gba ida rẹ ati pe kini ohun ti on yio ṣe ti ọwọ Ogun ko fi ni ka on: Ifa ni yan akukọ kan ti Ọrunmila ni, ati igbin mẹrin-dinlogun lati rubọ, Ọrunmila si rubọ na.

Ogun lọ si ọdọ Orișa o fi ida han an pe on ti gba a, nigbana ni Orișa tubo kọ Ogun pe ki o lọ gbẹsan lara Ọrunmila, ki o lo kọlu oko Ọrunmila, ti o mbẹ leti oko ọdọ on, Ogun ni on ko mọ ibiti oko na gbe wa, Orișa ni kosi ẹlomiran ti ọ ba on pẹlu Ọrunmila pāla oko si ibi kanna, bi Ogun b ti nlọ, ibiti o ba kọ gbo kekereke akukọ ki o ya si ibẹ, nitori oko Ọrunmila lo mbẹ ni akokan; bẹni Ogun fọn le ọna, șugbọn kọ gbọ ohun kikọ akukọ titi o rekọja oko ti Ọrunmila, nitori akukọ kan șoșo na ni Ọrunmila ti fi rubọ.

Ogun de iwaju tan ọ gbọ akukọ kọ, o rọ lu ibẹ, ki a șe gbogbo awọn enia ati gbogbo nkan ti o mbẹ ni ibẹ bi ọșẹ ti nșe oju, ki a nko gbogbo wọn mbọ wa si ile, ninu gbogbo eyi, o șebi oko Ọrunmila ni on lọ ja ni ogun, ki o to wọ ilu ni Ọrunmila ti pa igbin mẹrin-dinlogun na rubọ, o si fi karawun wọn kọ si ẹnu ọna ita rẹ bi Ogun ti mbọ ti o ri karawun igbin wọnni, o șebi ile Orișa ni, o bẹrẹ si yin Orișa pe o șeun fun ẹbọ ti o ru de on pe ki nkan ma șe on, nibiti on nlọ, gbogbo ikogun ti o ko ni oko Orișa lelẹ ni ita Ọrunmila, o wa sare lọ kọlu ile Orișa wayi o șebi ti Ọrunmila ni, ki a tun șe gbogbo ibẹ șukușuku, Orișa tikalararẹ kan lu igbẹ, o wa nkigbe wipe "On ni on șika mọ ara on bayi"!

Nigbati Ọrunmila gbọ sababi gbogbo nkan wọnyi, o wa bọ si ode o ko ilu o njo, eyi fihan pe "Ẹniti o kun'lẹ to gbin'ka ori oni'ka ni'ka ihu le."

Ki gbogbo awọn ẹniti o nhu iwa ika si ọmọ ẹnikeji wọn lọ șora gidigidi nitori ọjọ ti yio ku on nikan ani ọjọ ti a o bo ẹ mọlẹ bi ẹni sin ișu ti ọtitọ yio si han gedegbe.

Pupọ ọmọ Anabi Adamọ lo di ero ibomiran Ọgbagigi lai șẹ lai ro, tabi iru awọn ẹniti o ti fi itori ogun tabi alapa lasan-lasan di ẹni ilẹ.

Bi Ọlọrun ba ti șe itẹlọrun diẹ fun ẹlomiran o di wipe ki ẹlomiran ma sure rẹ kiri pe a șe oju on pẹlu rẹ a ti gun 'gi ọpọlọ oju ejo ni yio șe, gbogbo iru iwa gbogbo bẹ ni ọpọlọpọ fi nșe ayọ, șugbọn o yẹ ki a ran ara wa leti pe ki a lọ șora gidigidi, iku lo di meji okan yi, aisan lo ni on aisan yi, gbogbo rẹ lo di rudurudu lati ri torọ fi mu'kọ arọ, o di ișẹ, ki a ma șẹșẹ sọ a ti se kọtọ sinu ișasun bi ti atijọ fun ẹlomiran, bi ẹlomiran ba ti le jaja ri kobọ kan ẹja 'din elepinni pẹlu gari elepinni lo ma fi gbọ bi ọpa ọna Ejinri lo ma fi wa, bi fẹșẹlu ẹwẹ lo si ma fi ran, o dọwọ rẹ—ki lo fa gbogbo rẹ? a mọ ọ, a kole sọ ni.

Ẹ jẹki a ronu piwada, ilẹ nșu ilẹ nmọ, ki a si ranti pe Babalawo a ku, Onișegun a re ọrun, iku yio pa adahunșe ati gbogbo wa ko ni ku iku ikan nilẹ.

"Ẹniti o kun 'lẹ to gbin 'ka ori oni'ka ni'ka ihu le."

(*Koi ti pari.*)

Emi ni ti nyin nitotọ,
KEKERE-AWO.

## *Olusakin's Column.*

### Certificate of Honour.

"**In the name of His Majesty The King George the Fifth.**

This Certificate is issued to George Nicholas Martins of the Nigerian Customs Department, as a record of the valuable services rendered by him to his own Country and People unto the British Government in that he has been during thirty eight and a half years conspicuous for the loyalty and efficiency of his service to Government.

(Sgd) F. M. Baddeley,
*Officer Administering the Government.*"

Dated 4th June, 1928.

### Rev. J. O. Lucas
[ Inter B.D, London ]

News reached us that the Rev. J. Olumide Lucas, M.A., D.th., L.C.P., Senior Tutor C.M.S. Grammar School, Lagos, has successfully passed the Intermediate Examination in Divinity of the University of London—Congratulation.

### Theft of Two Pence Bread.

Kadiri Adepọju, 24, was charged before Police Magistrate, Ebute-Metta, on Saturday, the 24th instant, for stealing two pence worth of bread from a bread seller at Ereko market, Lagos, and sentenced to two days' imprisonment with six strokes. We advise Kadiri to find some job to do.

### Alleged Corruption in the London Police Force.

London, Monday.

As a sequel to the investigations of the corrupt practices of the Proprietors of London Night Clubs, Station Sergeant Goddard of the Vine Street Police Station, in London, who has a record of 25 years' service and was dismissed from the force on the 29th October, has now

been arrested and charged at the Bow Street Police Court for unlawfully and corruptly accepting a gift of £60 from Ribuff, the Assistant Manager of Uncles Club at Albemarle Street. The case has been remanded and bail was refused—*Reuter*.

---

Sir William Joynson-Hicks recently stated in the House of Commons that a sum of £12,000 was found in the possession of a certain Police Sergeant who obtained this sum from aliens running Night Clubs. This shows the startling extent to which corruption has been practised—*Reuter*.

---

## ABẸOKUTA.

---

## How are the Mighty Fallen.

Ikereku Church was packed full to the brim on Sunday, the 25th inst, on occasion of the "going out to Church" of the relatives of the late Mr. Feyisara Sopein. Apart from the congregation, a considerable number of friends and acquaintances from Lagos, Ibadan and other outlying districts constituted the mass.

The Rev. J. A. Fadipẹ the Pastor in Charge, preached a most lasting and impressive sermon worthy of the occasion. He took for his text a portion of the elegy upon Saul and Jonathan, according to Biblical writing "Have not the glorious heroes fallen"? And "How have the mighty fallen! And the arms of the warrior failed!" He recounted various noble acts bearing on the manifest chivalry that characterised the whole life of the deceased; really the whole congregation was lachrymosely moved. *Mens sana in corporesana*.

Special dirgical airs were prepared by the choristers for the occasion, the rendering and singing of which irresistibly set both the mourners and the congregation weeping. *Momento mori*.

The goodly number of attendance was an authentic indication of the high esteem in which Mr. Ṣopein was held by all sections of the community irrespective of religion. His untimely tragic death naturally means a good deal in the national progress of Egbaland. Standing by himself, the criticism and the opposition of Mr. Sopein against unwarrantable policy or measure by the authorities that are not calculated to make for as good and advanced government are always sound, reasonable and of just cause. A proverbial saying must undoubtedly linger long in anybody's lips in Abeokuta "While the cat is away, surely the rats will enjoy their liberty of rumours play with immunity." Our "F.S." is gone, *O tempora, O mores!*

To the family of the deceased, especially Barrister Omoliyi Coker his uterine brother we tender our heartfelt condolence. R.I.P.

**How are the Mighty Fallen!**

*The Nigerian Daily Telegraph 29/11/28.*

---

PRINCE ADEYEMI OF IFE.

Prince E. A. Adeyẹmi and Staff who arrived Lagos on Friday the 23rd November last, to witness the Dedication Service of African Cathedral Church, (Bethe) left for Ile Ifẹ on Wednesday last.

OLUṢAKIN.

---

## EKUTE TI O ṢE ALAIGBỌRAN.

Ni ọjọ kan ekute kan lọ wa onjẹ ti o ma jẹ ni alẹ ki o to sun. Bi o ti nlọ o pade ologbo kan ẹniti o sọ fun wipe ki o duro de on lati wa gba onjẹ ti on wa.

Ekute:—Oju rẹ ba mi lẹru, Ogboni!

Ologbo:—Mo fẹ fun ọ ni onjẹ ni.

Ekute:—Emi o lọ sọ fun iya mi ni ile bi o ba dara.

Ologbo:—O dara, ma lọ, emi o si ma duro de ọ o.

Ekute:—(Sure lọ) Iya mi, ọrẹ mi kan, oloju ti o da ẹru ba mi, ni on yio fun mi ni onjẹ o si duro de mi, mo wa sọ fun ọ ni, mo lọ (o nlọ.)

Iya rẹ:—Pada (o nsure lati ba pe e pada,) ẹniti o ri ni, ko ni onjẹ, kakabẹ pipa ni o ma pa ọ,

Ekute:—Oṣe! mo nlọ, bi mo ba gba de, o ki yio fi ẹnu kan ninu rẹ.

Iya rẹ:—Jọwọ maṣe lọ ọmọ mi, Adufẹ!

(Iya lọ sode, Ekute sa bọ sode tọ Ologbo lọ,)

Ekute:—Ọrẹ mi, maṣe binu pe mo pẹ, iya mi ni o dami duro.

Ologbo:—Iya rẹ na ma fẹran rẹ o.

Ekute:—Onjẹ na da, ọrẹ mi?

Ologbo:—(o ki mọlẹ) on ma ni o ri ni ẹnu mi yi; bi mo ba bu temi jẹ emi o wa fun ọ ni tirẹ.

Ekute:—Jọwọ on ko fẹ mọ, fi mi silẹ ki nma ba temi lọ.

Ologbo:—O ko tun wa si aiye yi mọ, ọrun ni o laju si nisisiyi (o gbe mi.)

Awọn ọmọ ti a ba wi fun ko gbọ, bi ko ba gbọ, iru ti Ekute alaigbọran yi ni nwọn o ma ri.

AGBEKẸ.


Disinfectant Soap of Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap Tablets
MAGNET SOAP
MAGNET
SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## Use Yaro for your baby!

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d & 2/3d.

## Increased health for 3/- only.

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers.

Price 3/- per bottle.

## A chance for female sufferers.

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness. Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs, cockroaches, etc., etc. 1/- and 1/6d per bottle.

### Anti-Gon Pills.

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills--a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

Glaxo (large and small sizes)
Vitafer—Brain Tonic
Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
Pile Pills 1/6
Vibrona Wine. 7/6
Lactogen
Kalzana
Effective Pile Remedy 7/6
Back and Kidney Pills 2/-
Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office:*—88, Broad Street, Lagos,
*Branches:*—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
27, Moloney Bridge Street
109, Griffith Street, Ebute Metta

## White's Golden Male Tonic

(DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### ARẸMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.
Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

(*A Native preparation for Women.*)

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".
Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILN ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, **Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.**

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

## TO LET.

One Splendid Pleasure Car
No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to:—
A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

———:o:———

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.